# AMU:
# AKUNGBA JOURNAL
# of the HUMANITIES

VOLUME 4, No. 1, September, 2022



AMU, domestic reservoir of refreshing
drinking water amongst the Yoruba, offers us
a perfect metaphor for the collection of highly
seminal, well-researched and referred
academic papers offered in this journal.

ISSN - 0795-2120
Published by the Faculty of Arts,
Adekunle Ajasin University, Akungba Akoko,
Ondo State, Nigeria.

AMU: AKUNGBA JOURNAL OF THE HUMANITIES
VOLUME 4, No 1, September, 2022

**Editorial Board**

| | |
|---|---|
| Professor Uriel Okunrinmeta | Editor-in-Chief |
| Professor O. Adebowale | Managing Editor |
| Professor B. M. Akinnawonu | Member |
| Professor B. O. Igboin | Member |
| Professor S. O. Ehiabhi | Member |
| Dr. A. A. Adegbamigbe | Business Manager |
| Dr. O. Rapheal | Secretary |

**Consulting Editors**

| | |
|---|---|
| Professor K. E. Obasola | Department of Religious Studies, Olabisi Onabanjo University, Ago-Iwoye |
| Professor Demola Jolayemi | Department of English, University of Africa, Toru-Orua, Bayelsa State. |
| Professor R. O. Ikotun | Department of Linguistics & Communication Arts, Osun State University, Osogbo |
| Professor Udoh Etuk | Department of Philosophy, University of Uyo, Uyo. |
| Professor Akanji Nasiru | Department of Communication & Performing Arts, Bowen University |
| Professor A. A. Bamidele | Department of English & Literary Studies Federal University, Lokoja |
| Professor Olayemi Akinwumi | Department of History & International Studies, Nasarawa State University, Keffi |

AMU: Akungba Journal of the Humanities is an annual multidisciplinary journal. Its focus is on the publication of the latest scholarly papers within the context of international best practices. The journal is published annually by the Faculty of Arts, Adekunle Ajasin University, Akungba- Akoko, Ondo State, Nigeria.



The journal calls for well researched and incisive scholarly papers for publication in **Volume 5, No 1** edition of the journal. The journal covers the fields of English Studies, History, Linguistics, Philosophy, Religious Studies, Performing Arts and Yoruba. The journal encourages submissions of high quality, original papers which have not been submitted for publication elsewhere.

Manuscripts should be written in clear English/Yoruba language and should not exceed 15 pages, typed in MS Word format in 12pt font size, Times New Roman and 1.5 line spacing. The paper should be accompanied with an abstract of not more than 250 words and five keywords. The front page of the paper must contain the title, names and institutional affiliation of the author. Tables and figures should carry titles, relate directly to the text and be easily comprehensible. Citation of sources should be indicated in Arabic figures in the text consecutively, with superscript numbers, and should be explained in a list at the end of the text as Endnotes. Reference citations in the text should follow the Turabian manual citation. For instance, Book Citation: Uriel O. Okoye, *Practical English in Nigeria* (Lagos: Longman, 2010), 79. Journal Citation: C. O. Adams, "The Ekiti Parapo War of the 18th Century", *Akungba Journal of History* 5.2 (December, 2012): 67-9. Joint authorship of three or more names, the words "et al" Should be inserted after the first name). The use of ibid, op cit. etc are not accepted. In case of repeated citation, such should be spelt out. Taking a cue from the above, what is needed is Uriel O.Okoye, *Practical English in Nigeria.*

Manuscript Submission Deadline: 31st July, 2023

- The Assessment fee per article is ₦5,000
- Authors of accepted papers are required to pay a

publication fee of N25,000 within 14 days of notification of acceptance.

- Foreign contributors are to pay $100.
- Payment should be made to: **Account Name:** AMU: Akungba Journal of Humanities, **Account Number:** 0775072792, Bank: Access
- Scanned copy of payment details should be forwarded to amu.humanities@aaua.edu.ng
- All enquiries and submissions should be forwarded to the Secretary. AMU: Akungba Journal of the Humanities, Faculty of Arts.amu.humanities@aaua.edu.ng

Copyright, Faculty of Arts, Adekunle Ajasin University, P.M.B 001, Akungba-Akoko, Ondo State, Nigeria.



**Notes on Contributors**

OTTUH, Peter O. O. is an Associate Professor in the Department of Religious Studies and Philosophy, Delta State University, Abraka, Delta State, Nigeria

MAJEMIT, Anthony is of the Department of Religious Studies and Philosophy, Delta State University, Abraka, Delta State, Nigeria.

'DUNMADE, Femi is a Lecturer in the Department of English, University of Ilorin, Ilorin, Nigeria.

ODENEYE, Adesola Rasidat is a Lecturer in the Department of English, School of Languages, Tai Solarin College of Education, Omu-Ijebu.

ONOJA, Ikuwta Augustine is a Lecturer in the Department of History and Diplomatic Studies, Federal University, Kashere, Gombe State.

KEHINDE, Ayobami is a Professor in the Department of English University of Ibadan, Ibadan.

ASIWAJU, Jumoke Helen is a Lecturer in the Department of linguistics & languages, Faculty of Arts, Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko, Ondo State, Nigeria.

OKEWANDE, Oluwole Tewogboye is a Lecturer in the Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilorin, Ilorin.

FARINDE, Raifu Olanrewaju is a Lecturer in the Department of English and Literary Studies, Federal University Oye-Ekiti, Nigeria & FARINDE, Muibat Abiola is a Lecturer in the Department of Yoruba, Adeyemi College of Education, Ondo.

publication fee of N25,000 within 14 days of notification of acceptance.

- Foreign contributors are to pay $100.
- Payment should be made to: **Account Name:** AMU: Akungba Journal of Humanities, **Account Number:** 0775072792, Bank: Access
- Scanned copy of payment details should be forwarded to amu.humanities@aaua.edu.ng
- All enquiries and submissions should be forwarded to the Secretary. AMU: Akungba Journal of the Humanities, Faculty of Arts.amu.humanities@aaua.edu.ng

Copyright, Faculty of Arts, Adekunle Ajasin University, P.M.B 001, Akungba-Akoko, Ondo State, Nigeria.



## Notes on Contributors

OTTUH, Peter O. O. is an Associate Professor in the Department of Religious Studies and Philosophy, Delta State University, Abraka, Delta State, Nigeria

MAJEMIT, Anthony is of the Department of Religious Studies and Philosophy, Delta State University, Abraka, Delta State, Nigeria.

'DUNMADE, Femi is a Lecturer in the Department of English, University of Ilorin, Ilorin, Nigeria.

ODENEYE, Adesola Rasidat is a Lecturer in the Department of English, School of Languages, Tai Solarin College of Education, Omu-Ijebu.

ONOJA, Ikuwta Augustine is a Lecturer in the Department of History and Diplomatic Studies, Federal University, Kashere, Gombe State.

KEHINDE, Ayobami is a Professor in the Department of English University of Ibadan, Ibadan.

ASIWAJU, Jumoke Helen is a Lecturer in the Department of linguistics & languages, Faculty of Arts, Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko, Ondo State, Nigeria.

OKEWANDE, Oluwole Tewogboye is a Lecturer in the Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ilorin, Ilorin.

FARINDE, Raifu Olanrewaju is a Lecturer in the Department of English and Literary Studies, Federal University Oye-Ekiti, Nigeria & FARINDE, Muibat Abiola is a Lecturer in the Department of Yoruba, Adeyemi College of Education, Ondo.

Table of Contents


| | Pages |
|---|---|
| 1. Foreword - *Managing Editor* | 7 |
| 2. Assessing the Impact of Mixed-Marriage on Socio-Religious Integration in Nigeria - OTTUH, Peter O. O. & MAJEMIT, Anthony | 8-28 |
| 3. A Postcolonial Criticism of Wole Soyinka's Relief or, Wedding in a Minor Key' - 'DUNMADE, Femi | 29-47 |
| 4. A multimodal Discourse Analytical Study of Selected Online Christian Inspirational Posts - ODENEYE, Adesola Rasidat | 48-65 |
| 5. A Study of Agila and Ezza-Igbo Diplomatic Relations from 1700-1900: Implication on Inter-group Relations - ONOJA, Ikwuta Augustine | 66-95 |
| 6. Narrating the Continent: The Nexus of Social Realism and Postmodernist Aesthetics in the Contemporary African Novel - KEHINDE, Ayobami | 96-125 |
| 7. Ilo Orin Ninu Asayan Itan-Aroso Onkowebinrin Yoruba - ASIWAJU, Jumoke Helen | 126-156 |
| 8. Ifa/Orunmila bi Onimo-ede Pupo: Eri latinu Ohun Enu Ifa - OKEWANDE, Oluwole Tewogboye | 157-180 |
| 9. Code-Switching in Nigerian Yoruba Movies: Examples of Ese Ni and Gbemileke - FARINDE, Raifu Olanrewaju & FARINDE Muibat Abiola | 181-198 |




# FOREWORD

The incessant disruptions in the University system due to the global epidemic lockdown and other unforeseen circumstances adversely affected the publication of *AMU* in the last three years. However, all the obstacles militating against its regular publication has been surmounted.

The primary aim of *AMU: Akungba Journal of the Humanities* is to create a platform for national and international scholars and students to present well researched, scholarly articles that would be peer reviewed for publication.

This current issue presents a wide range of 8 academic articles covering the disciplines of English Studies, History, Yorùbá Studies, Religious Studies and Philosophy. The papers which are presented in clear English/Yorùbá Language address diverse issues of interest ranging from social realism and postmodernist criticism of the novel to post colonial criticism of poetry. The implication of diplomatic relations on inter group relations, socio-religious integration of mixed marriages, discourse analysis of online Christian inspirational posts and issues in cultural studies were also interrogated.

Our contributors were drawn from the mid-career academics to those in the professorial cadre across institutions in Nigeria. It is our hope that the next edition of the journal will feature papers with multidisciplinary approach and contributors from other continents.

I appreciate members of the Editorial Board for their cooperation in ensuring the success of this edition and on their behalf present the 2022 edition.

Rájí, S.M. (1987)."Orin-Ọtẹ̀", Unpublished M.A Thesis, Department of Linguistics and African Languages and Literature. Ọbafẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Ilé-Ifẹ̀.

Rájí, S.M. (2011). "Ìṣọwọ́lò-Èdè Inú Orin àti Ewì Àlàbí Ògúndépọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ọnà Èdè", *Ẹ̀gìn Jọ́nàlṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, o.i.24-34.

Rájí, S.M. (2014). "Àgbéyẹwò Ojú Àmúwáyé àti Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá nínú Orin Àjẹmẹ́sìn Mùsùlùmíní ilẹ̀ Yorùbá" Unpublished PhD Thesis, Department of Linguistics and African Languages and Literature, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Ilé-Ifẹ̀, 2014.

Sànyà, A.G. (2001). "Orin Ìjó Yorùbá nínú Ìdàgbàsókè Ilẹ̀ Nàìjíríà" Unpublished mimeo.





# Ifá/Ọ̀rúnmìlà bí Onímọ̀-èdè Púpọ̀: Ẹ̀rí látinú Ohùn

**Oluwọle Tẹwọgboye OKEWANDE**
*Department of Linguistics and Nigerian Languages,*
*University of Ilorin, Ilorin.*
*oluwoletewogboyeokewande@gmail.com*
*okewandeo.t@unilorin.edu.ng*

**Àṣamọ̀**

Ifá jẹ́ ọpákùtẹlẹ̀ tó gbé àṣà Yorùbá ró, nípa bẹ́ẹ̀, ó fẹ́rẹ̀ n ìgbé-ayé Yorùbá tí a kò lè tọpinpin dé inú Ifá. Èdè jẹ́ ọka nínú àṣà àwùjọ ọmọnìyàn, èyí kò sì yọ àwùjọ Yorùbá sílẹ̀ rá ẹ̀ka-jẹ̀ka ìgbé-ayé Yorùbá, tó tan mọ́ Ifá ni iṣẹ́ ìwádìí ti w wọn. Àmọ́ sá, títí di àsìkò yìí, iṣẹ́ ìwádìí èdè inú Ifá, ní pàt kan èdè mìíràn bí ẹ̀dè Tápà (Nupe), Haúsá àti Lárúbáwá kò bí èyí tíṣẹ́ ìwádìí yìí dágbálé. Ìlànà ìtàn ni iṣẹ́ yìí ṣan ìtọpinpin ìwádìí, ní pàtàkì, ìtàn Ifá. Iṣẹ́ ìwádìí yìí fi Ọ̀rúnmìlà, tíí ṣe òngbufọ̀ tàbí agbẹnusọ Ifá jẹ́ onímọ̀ è Haúsá àti Lárúbáwá, àwọn èdè tó sọ Òrìṣà yìí di gbajúgbaj èdè púpọ̀, bó ti jẹyọ nínú ìmédèlò àwọn èdè wọ̀nyí nínú od yìí ṣàmúlò fún ìtúpalẹ̀. Iṣẹ́ ìwádìí yìí fi hàn pé, àkọ́ọ́nú àti ìpò ìjẹyọ ẹsẹ àti odù-Ifá tayọ èdè Yorùbá nìkan. Àgbálọgb ìwádìí yìí fìdí ìbátan àti ìmọ̀ Ifá àti Ọ̀rúnmìlà hàn bí èyí tó t àti àwùjọ Yoruba nìkàn, ṣùgbọ́n, tó ṣàmúlò ìmọ̀ èdè àti àṣ mìíràn bákan náà.

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Ifá, Ọ̀rúnmìlà, odù Ifá, èdè, elédè-púpọ̀, ìmọ̀-ìtà

## Ìfáàrà

Ifá jẹ́ ìpìlẹ̀ tàbí ọwọ̀n tó gbé àṣà Yorùbá- báyéṣẹ ìjìnlẹ̀-èrò, ìgbàgbọ́, iṣe, ẹ̀sìn tó fi kan èdè rò; nípa báyìí, ọ

ìgbé-ayé Yorùbá ni a lè tọpinpin dénú Ifá. Ọrúnmìlà ni Òrìṣà tí a fi ohùn-ẹnu Ifá rán (bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àwọn onímọ̀ kan gbà pé kò sí ìyàtọ̀ láàárín Ifá àti Ọrúnmìlà). Káàkiri àgbáyé ni èdè (yálà alohun, alákọ̀ọ̀lẹ̀, àmì, amí tàbí ohùn) ti jẹ́ kóríkó-o-yá pẹ̀lú ìgbé-ayé àti ìmúdúró àwùjọ ọmọnìyàn, nítorí, nípasẹ̀ èdè ni a fi ń mọ èrò ọkàn ènìyàn, àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ìbátan láàárín ara-ẹni tàbí nínú àwùjọ. Síṣọ èdè mìíràn yàtọ̀ sí èdè abínibí jẹ́ ọ̀nà kan láti ṣàfihàn àjọṣepọ̀ àti ìbátan pẹ̀lú ẹ̀yà mìíràn. Iṣẹ́ ìwádìí yìí wáyé láti tọpinpin àmúlò tàbí ìjẹyọ ohùn ẹnu Ifá dé inú èdè Tápà (Nupe), Hausá àti Lárúbáwá, èyí tó ṣàfihàn Ifá bí onímọ̀ àti ẹni tó gbọ́ àwọn èdè wọ̀nyí. Èyí túmọ̀ sí pé, àjọṣepọ̀ tàbí ìbátan lọ́nà kan tàbí òmíràn wà láàárín Ọrúnmìlà àti àwọn èdè wọ̀nyí. Ìlànà ìtàn, pàápàá, ìtàn Ifá ni iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣàmúlò; níwọ̀n igbà tí "*ẹsẹ Ifá* is historical in content; its structure is also based on its historical nature."[1] Èyí ni pé, àkóónú ẹsẹ-Ifá jẹ́ ajẹmọ́tàn; bẹ́ẹ̀ sì ni ìhun rẹ̀ náà dúró lórí ìṣẹ̀dá ajẹmọ́tàn. Ṣáájú àkókò yìí, kò tíì sí iṣẹ́ ìwádìí tí a mọ̀, tó tọpinpin tàbí ṣàfihàn àjọṣepọ̀ èdè mìíràn (tayọ èdè Yorùbá) nínú Ifá. Nítorí náà, iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣàfihàn àjọṣepọ̀ ìbátan ìtàn èdè Yorùbá pẹ̀lú èdè Tápà, Hausá àti Lárúbáwá èyí tó júwe Ọrúnmìlà bí onímọ̀ èdè púpọ̀ nípa bí àwọn èdè wọ̀nyí ṣe jẹyọ nínú ìmẹ́dèlò ohùn ẹnu Ifá.

## Ìlànà Ìwádìí

Ìlànà ìwádìí ajẹmọ́tàn ni iṣẹ́ yìí gùn lé; bí ó ti jẹ́ pé, ó fẹ́rẹ̀ẹ́ máà sí ẹ̀ka ìgbé-ayé Yorùbá: ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò, ìṣẹ̀lú, ọrọ̀-ajé, sáyẹ́ǹsì, ìbágbépọ̀-àwùjọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí kò sí nínú Ifá;èyí tí kò yọ ìmọ̀ ìtàn sílẹ̀. Oríṣìí ẹ̀ka-ìmọ̀ ìtàn Yoruba ló lè jẹ́ àmúlò fún ìwádìí- ìtàn ìgbànnì, ìtàn àlọ́, ìtàn mẹ́rìírí, ìtànyítàn àti ìtàn Ifá. Ìtàn Ifá ni iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ṣatẹ̀gùn ìwádìí; nítorí, "lítíréṣọ̀ tó pinmirin kún inú ohùn ẹnu Ifá fọ́fọ́."[2] Púpọ̀ ẹ̀ka lítíréṣọ̀ Yorùbábí i ọ̀fọ̀, oríkì àti orílẹ̀





ló máa ń ṣàmúlò ìmọ̀ ìtàn.

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ẹ̀ka-ìmọ̀ ìtàn ló kúnnú Ifá: ìtàn òrìṣà, a[...] ajogun àti ẹlẹyẹ, ènìyàn, àwọn ẹ̀mí-àìrí, ìlú, àwọn akọni, ẹrank[...] ẹran-ọ̀sìn, ẹyẹ, kòkòrò, igi, ohun-ọ̀gbìn, òkú-ọ̀run àti bẹ́ẹ̀ lọ. Abímbọ́lá wòye pé, ìwádìí ajẹmọ́tàn inú ẹsẹ-Ifá "is importa[...] a source of information on Yoruba cultural history which is [...] neglectd by the Western-trained historian." Èyí túmọ̀ sí pé, I[...] pàtàkì bí orísun ìtàn àṣà Yoruba èyí tí àwọn akọ̀ṣẹ́mọṣẹ́-onímọ̀[...] ìgbàlódé máa ń fojú tínínrin.[3] Amúlò ìjẹyọ èdè mìíràn-Tápà, H[...] àti Lárúbáwá (yàtọ̀ sí èdè Yoruba) yóò ṣàfikún ìmọ̀ tí a ti ní tẹ́lẹ̀ [...] èdè Ifá. Iṣẹ́ yìí yóò ṣe àgbéyẹ̀wò èdè àmúlò ẹnu Ifá tayọ èdè Yo[...] tí a ti mọ̀ ọ́n mọ̀ ṣáájú àkókò iṣẹ́ ìwádìí yìí.

## Èrò àwọn onímọ̀ nípa Ifá àti Ọrúnmìlà

Bí a bá ní bí ẹjọ́ ṣe gùn tó la ó ṣe dáná rẹ̀ gbogbo igi igb[...] ó fẹ́ẹ̀ lọ tán, nítorí, títí di àkókò yìí, ẹnu àwọn onímọ̀ kò ko[...] nǹkan kan náà ni Ifá àti Ọrúnmìlà tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Nítorí náà, ọ̀rọ̀ ì[...] àti ìyapa láàárín Ifá àti Ọrúnmìlà tayọ èyí tíṣẹ́ yìí lè dágbálé. E[...] ni iṣẹ́ yìí yóò sọ nípa èyí. Nínú èrò Adéoyè, ìsọ̀rí méjì ni èrò onímọ̀ pín sí nípa Ifá àti Ọrúnmìlà. "Àwọn ìsọ̀rí kìíní nínú olùwádìí wọ̀nyí gbà pé kò sí ìyàtọ̀ nínú 'Ifá' àti Ọ̀rúnmìlà. Àb[...] ìwádìí wọn ni pé, ẹnìkan náà ni ń jẹ́ orúkọ méjèèjì. Ìsọ̀rí mìírà[...] pé ọ̀nà tí Ọ̀rúnmìlà ń gbà ṣe iṣẹ́ rẹ̀ àti ohùn tí ń fọ̀ lẹ́nu bí ó b[...] ènìyàn lọ́wọ́ kan ìbò wò ni 'Ifá' àti pé, ìrúnmọlẹ̀ tí ó ń ṣiṣẹ́ 'Ọ̀rúnmìlà'"[4] Bákan náà, lójú Ọdẹ́gbọlá, "Ọ̀rúnmìlà kìí ṣe Ifá[...] Ohùngbìfọ̀ Ifá ni."[5]

Lójú Akìwọwọ, a lè pe Ọ̀rúnmìlà ní ọ̀ngbufọ̀ Ifá. Ìdí [...] fi ṣàkàwé ìmọ̀ Ọ̀rúnmìlà bí "àmọ̀imọ̀tán", nítorí, ìmọ̀ tó wày[...] Ọrúnmìlà ni. "We know there exists such an entity as Ọ̀rú[...] We know many of his attributes; but he possesses others whi[...]

do not yet know and must struggle to discover for the rest of the period of our human existence. For he is àmọ̀ìmọ̀tán."' Èyí túmọ̀ sí pé, ẹnìkan wà nígbà kan rí tó ń jẹ́ Ọ̀rúnmìlà. Púpọ̀ àwọn abúdá rẹ̀ ni a mọ̀, ṣùgbọ́n ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn àbùdá ló ní tí yóò jẹ́ mímọ̀ nípasẹ̀ akitiyan ìwádìí, nítorí, ojú kò lèè pin ìmọ̀ tó ní.[6] Àmọ́ sá, èrò Abímbọ́lá nínú ìwádìí rẹ̀ sọ pé, "the fact borne out of my own research, however, is that the two names, *Ifá* and *Ọ̀rúnmìlà* refer to the same deity." Èyí túmọ̀ sí pé, iṣẹ́ ìwádìí mi fihàn pé ọ̀kan ni àfipè Ifá àti Ọ̀rúnmìlà já sí.[7]

Èrò Orímóògùnjẹ́ ni pé, àgbéyẹ̀wò èrò àwọn onímọ̀ nípa Ifá àti Ọ̀rúnmìlà ṣàfihàn ìjọra mẹ́ta pàtàkì: "Ọ̀rúnmìlà, ọ̀rọ̀ àti Olódùmarè."[8] Síwájú sí i, onímọ̀ yìí fi ojú ọ̀tun wo àjọṣepọ̀ tó wà láàárín Ifá àti Ọ̀rúnmìlà. Ó pabì, ó sì yàbìdun rẹ̀ pé "kì í ṣe pé bóyá Ifá jẹ́ Olódùmarè; tàbí pé Ifá náà ni Ọ̀rúnmìlà; bẹ́ẹ̀ sì ni kì í ṣe Ọ̀rúnmìlà, ọ̀rọ̀ àti Olódùmarè ni wọ́n papọ̀ tí wọ́n ń pè ní Ifá; ṣùgbọ́n Olódùmarè gan-an ni Ifá."[9] Ìhà ọ̀tun yìí ni onímọ̀ yìí ṣe ẹ̀kárìkà àpẹẹrẹ àtìlẹ́yìn èrò rẹ̀ dénú ẹ̀sìn mìíràn, pàápàá, inú Bíbélì. Àgbéyẹ̀wò Ifá tàbí Ọ̀rúnmìlà bí "ọ̀rọ̀ gbogbo-èdè: Olódùmarè" jẹ́ ẹ̀rí mìíràn pé, abùdá Olódùmarè, tí kò sédè tí kò gbọ́ nì Ifá tàbí Ọ̀rúnmìlà dúró fún. Àmọ́ sá, kò sí ẹ̀rí láti fi àwọn àpẹẹrẹ èdè ẹnu Ifá tàbí Ọ̀rúnmìlà múlẹ̀ ṣáájú iṣẹ́ ìwádìí yìí. Ohun tí ó hàn gbangba ni pé, ẹran lójú, gbòdògì sì láàlà ni ìhà ìkọsíra Ifá àti Ọ̀rúnmìlà, síbẹ̀, bí a bá ń yin ẹtù, orí awó a sì má a wú; bẹ́ẹ̀, bí a bá sì ń bú ẹtù, orí a sì máa fọ́ awó lọ́rọ̀ ìbátan Ifá òun Ọ̀rúnmìlà. Ọ̀rọ̀ tó bá ti kan ìsaasùn yóò kan ṣíbí, ohun tó bá ti kan Ìgè, kò le yọ Àdùbí sílẹ̀; nítorí, bí a bá ti fa gbùrù ni, dandan ni kí gbùrù náà fagbó.

Ifá, bí orúkọ ni àwọn orílẹ̀-èdè ń dá pè lórísìírísìí, kì í ṣe Ọ̀rúnmìlà., nítorí, ìlúmọ̀míká òrìṣà níí ṣe. Bí àpẹẹrẹ "Fá" ni àwọn ẹ̀yà Fọn nílẹ̀ olómìnira Benin mọ̀ ọ́n sí. "Eva" ni ẹ̀yà Tápà ń pè Ifá. Ifá náà ni à ń pe irúnmọlẹ̀ yìí ní Cuba, USA, Brazil, Trinidad àti





Tobago, Jamaica àti Togo. "Éfódù" ni àwọn Júù ń pe Ifá; nígbà tí ẹ̀yà Ewe ń pè é ní Afa.[10] Èyí ṣàfihàn pé, Ifá ti di ìlúmọ̀míká káàkiri agbáyé. Robinson ṣàfihàn rẹ̀ pé, "in 2005, the United Nations Educational, Scientific and Cultural Organisation (UNESCO) proclaimed *Ifá* as one of the 86 traditions of the world to be recognised as masterpiece of oral and intangible heritage of humanity."Èyí túmọ̀ sí pé, lọ́dún 2005 ni àjọ tó wà fún ètò ẹ̀kọ́, sáyẹ̀nsì àti àṣà lábẹ́ àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé kéde Ifá bí ọ̀kan lára 86 àṣà àgbáyé tó kópa lórí ìgbé-ayé ọmọnìyàn.[11]

Ipa kẹ̀rẹ́mí kọ́ ni Ifá kó nínú àṣà Yorùbá, nítorí, ìmọ̀ Ifá ni a fi ń tọpinpin àṣà Yorùbá. Ìdí rẹ̀ nìyí tí Abímbọ́lá fi rí Ifá, "as store house through which the Yorùbá comprehend their own historical experience and understand their environment." Èyí túmọ̀ sí pé,bí ilé-ìkẹ́rùsí ìṣẹ̀mbáyé tí ìran Yorùbá fi lè lóye àti ìmọ̀ ìrìrí ìtàn àwùjọ ni Ifá jẹ́.[12] Kódà, Ọbáyẹmí ní, òfegè ni àṣà tàbí ìṣe tí a kò bá lè tọpinpin dénú Ifá jẹ́ sí ìran Yorùbá, nítorí pé, "Ifá is fundamental in the explanation of the components of the Yorùbá culture." Ìtumọ̀ èyí ni pé, Ifá ṣe pàtàkì láti lè ṣàlàyé àwọn ẹ̀yà-ara àṣà Yorùbá.[13] Ohun, àṣà, ìṣe tí a kò bá lè tọpinpin dé inú Ifá àfàìmọ̀ kó máà jẹ́ ayédèrú tàbí àjèjì sí ìran Yorùbá. Ládélé àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ jẹ́ kó yé wa pé, "nínú Ifá ni a ti lè rí ìjìnlẹ̀ Yorùbá tí kò ní àbàwọ́n…Ìtàn t'ó farasin, ìtúmọ̀ orúkọ tí ó farasin, àti lítíréṣọ̀ t'ó pinmirin kún inú ohùn ẹnu Ifá fọ́fọ́.[14] Areoye ní, ọ̀kan lára àbùdá àwọmọ́ ẹsẹ-Ifá ni pé, "kò fi ààyè sílẹ̀ fún àfibọ̀ tàbí àtọwọ́dá."[15] Èrò yìí ṣàfihàn pé, ohùn ẹnu Ifá kò ṣe é ṣe àdàlù. Kò fàyè gba dída lùrú pọ̀ mọ́ ṣàpà rárá. Odindi tí ataare má a ń di tirẹ̀ ni odù àti ẹsẹ Ifá jẹ́. Ọ̀kan lára ìpèníjà àwọmọ́ tó farasin nípa Ọ̀rúnmìlà ni pé, olùgbọ́, olùsọ àti onímọ̀ èdè púpọ̀ (yàtọ̀ sí Yorùbá) ni í ṣe; èyí tiṣẹ́ ìwádìí yìí dágbá lé láti ṣàwárí ìfidí rẹ̀ múlẹ̀.

**Ìtàn Èdè àti Ẹ̀yà Yorùbá Pẹ̀lú Ifá àti Ọ̀rúnmìlà**

Níwọ̀n ìgbà tí "Yorùbá" bí èdè àti ẹ̀yà kò ti ṣe é yà nípa, tí "Yorùbá" sì jẹ́ èdè àmúlò àti ìṣafọ̀ ohùn ẹnu Ifá, ó yẹ láti tọpinpin orírun orúkọ yìí. Bí àpẹẹrẹ, orísìírísìí orúkọ àpèmọ́ àti orísun irú orúkọ bẹ́ẹ̀ (Yorùbá) ni àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ lé lórí. Lára irú orúkọ ìṣaájú tí a mọ ẹ̀yà Yorùbá mọ̀ ni *Ulkami/Ulkum/Alkamy/Lucumi*, tí a fi ń pe ẹ̀yà Yorùbá nílẹ̀ Cuba nígbà kan rí.[16]

Orúkọ mìíràn tí a fi ń pe ẹ̀yà Yorùbá ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni 'Akú', èyí tó jẹ jáde láti ara ìṣe ìkíni ẹ̀yà Yorùbá. Ní nǹkan bí ọdún 1787 nílẹ̀ Sàró (Sierra Leone), níbi tíjọba Gẹ̀ẹ́sì (British Government) ń kó àwọn tó gba ìtúsílẹ̀ tàbí ìdáǹdè kúrò lóko ẹrú sí. Awoniyi wòye pé, 'Akú' jẹ jáde láti inú ìpèdè ìkíni "A kún/Ẹ kún."[17] Àmọ́ sá, kò sí èyí tó gbajúgbajà bí 'Yorùbá.' Awóníyì tẹ̀síwájú pẹ̀lú èrò yìí pé, "None of these terms, largely coined for both the Yorùbá-speaking people and their language, survived in the Western State of Nigeria. It is 'Yorùbá' as a name which has endured. But the available evidence also points to the fact that the term 'Yorùbá' was a foreign-coined name, the origin of which is still shrouded in misery." Èrò yìí túmọ̀ sí pé, kò sí nínú àwọn orúkọ wọ̀nyí tí a rọ̀ tàbí dà pè láti tọ́ka sí ẹ̀yà àti èdè Yorùbá tó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láàrin àwọn Yorùbá, lápá ìhà ìwọ̀-oòrùn ìlẹ̀ Nàìjíríà. 'Yorùbá' bí orúkọ ló fẹsẹ̀ rinlẹ̀ jù. Àmọ́ṣá, àwọn ẹ̀rí tó wà ní àrọ́wọ́tó ṣàfihàn pé, àjèjì ni orúkọ 'Yorùbá' jẹ́, èyí tó sì tún rúni-lójú.[18]

Awoniyi ní, Òyìnbó aláwọ̀ funfun, Bowdich ni a kọ́ rí tó ṣàmúlò orúkọ tó fara pẹ́ tàbí tó jọ "Yorùbá." "Yariba" ló pe ẹ̀yà àti èdè Yorùbá, bí àṣà àwọn tí Bowdich júwe bí i 'Moor', ṣùgbọ́n, "Yarba" ni Yorùbá ń pe ara wọn nígbà náà. Àwọn 'Moor' ni Bowdich pè ní ẹ̀yà Hausá.

> *The Moors to which Bowdich referred, were the Hausa-speaking peoples who were the northern neighbours of the once great Ọy (Yorùbá) Empire of the seventeenth an eighteenth centuries.*





*The impression which seems to be created b Bowdich's comments is that the term 'Yorùbá was the name coined for the Yorùbá-speakin peoples by the Hausas. This may be true to certain extent, for the oral traditions of th Hausa peoples, as well as their records, appea to give an indication of a distant mythologica relationship with the Yorùbá-speaking people. For instance, in the Bayajida legend by whic the Hausa peoples traced their ancestra origin, it was claimed that the Yorùbá State wa one of the seven 'bastard' Hausa states. In th Hausa language, Yorùbá people are calle 'Yarabawa'; a Yorùbá man, 'Bayaraba'; an Yorùbá woman, 'Bayarabiya'; and the Yorùb language, 'Yarabanci.' However, all th hitherto available oral traditions of the Yorùba speaking people, and the interpretation of thes historical data by the historians of the Yorùb people made no reference whatsoever to th Hausa legend mentioned above with regard t their historical origins. Rather, the evidenc seems unamimous on the mythologica Odùduwà as the progenitor of the Yorùb peoples. The Hausa legend may therefore b nothing more than a reference to a very distan socio-political contact between the Hausa an*

> *the Yorùbá peoples in the past which has faded into mythological account.*
>
> Àwọn Moors tí Bowdich ń wí níbí ni àwọn tó ń sọ èdè Hausa tí wọ́n jẹ́ alámùlétì pẹ̀lú ìjọba ìlúmọ̀míká Ọ̀yọ́ níhà àríwá òkè-ọya ní sẹ́ńtíúrì kẹtàdínlógún àti ìkejìdínlógún. Ohun tí Bowdich ní lérò pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí a mọ̀ sí 'Yorùbá' ni àwọn tó ń sọ èdè Yorùbá ni pé àwọn Hausa sọ lóókọ yìí. Èyí lè jóòtọ́ dáàyè kan, nítorí ìtàn àtẹnudẹ́nu àti àkọọ́lẹ̀ àwọn Hausa ṣe àfihàn ìbátan tó jìnnà síra wọn pẹ̀lú àwọn tó ń sọ èdè Yorùbá Bí àpẹẹrẹ, nínú ìtàn ìgbaani Bayajida nípasẹ̀ ẹni tí Hausa tọpasẹ̀ ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn baba-ńlá wọn, wọ́n fi hàn pé Ìpínlẹ̀ Yorùba jẹ́ ọ̀kan lára ìpínlẹ̀ 'ọmọ àlè' méje Haúsá….'Yarabawa' ni Hausa n pe ìran Yorùbá, 'Bayaraba' ni ọkùnrin Yorùbá, tí obìnrin sì jẹ́ 'Bayarabiya'; nígbà tí wọ́n ń pe èdè Yorùbá ní 'Yarabanci'… Àmọ̀ sá, gbogbo ìtàn alohùn àwọn Yorùbá tó wà ní àrọ́wọ́tó tàbí ìtumọ̀ àwọn ìtàn tí àwọn onímọ̀ ìtàn ṣàwárí kankan kò tọ́ka sí ìtàn ìgbànnì Hausa kankan bí èyí tí Yorùbá fi sun jáde láti ara Hausa. Àwọn ẹ̀rí tí kò ní àtakò wà nínú ìtàn pé Odùduwà ló ṣe ìran Yorùbá sílẹ̀. Nítorí náà, ìtàn Ìgbànnì Hausa kò ní nǹkan mìíràn ju èyí tó ń tọ́ka sí àjọṣepọ̀ ẹ̀yà Yorùbá àti Hausa nídìí ọ̀rọ̀ amúlùúdùn-ọ̀ṣẹ̀lú tó ti wáyé tipẹ́ tipẹ́.[19]

Lọ́nà àkọ́kọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ẹ̀rí máa jẹ́ mi ń ṣó kò sí fún ìfẹsẹ̀ múlẹ̀ ìjóòtọ́ èrò òkè yìí, ohun tó ṣe pàtàkì nínú àyọlò yìí pẹ̀lú ìṣẹ̀ ìwádìí





yìí ni pé, ìṣàlàbàápàdé èdè Haúsá nínú ẹsẹ àti odù Ifá, tíṣẹ́ gbéyẹ̀wò ṣe é ṣe kó jẹ́ nípasẹ̀ àmùlétì ẹ̀yà Yorùbá pẹ̀lú Hausa

Nínú èrò mìíràn, kí Yorùbá, bí orúkọ àjùmọ̀jẹ́ ẹ̀ka-èdè tó wáyé, Ọ̀yọ́ nìkan ni a mọ̀ mọ Yorùbá. Lijadu ní:

> *it is perhaps necessary to state for the benefits of readers unfamiliar with Yoruba history that the people who came to be known later by the name are African sub-tribe in Nigeria such as Ifẹ̀, Ọ̀yọ, Ìjẹ̀ṣà, Ìjẹ̀bú, Ekìtì, Ondó, Ọ̀wọ̀, Èkó and so on, who share a common culture. In actual fact the name Yoruba was initially applied only to the Ọ̀yọ́ stock by their northern neighbours across the River Niger, the Hausa, before it was extended to embrace the whole ethnic unit.*
>
> Bóyá ó ṣe pàtàkì láti ṣàfọ̀mọ́ rẹ̀ fún àwọn òǹkàwé tí ìtàn Yorùbá ṣàjòjì sí pé ìran Yorùbá jẹ́ ara ẹ̀yà Adúláwọ̀ tí wọ́n ń jẹ́ àwọn orúkọ bí i Ifẹ̀, Ọ̀yọ́, Ìjẹ̀ṣà, Ìjẹ̀bú, Èkìtì, Òndó Ọ̀wọ̀, Èkó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, tí wọ́n ní àṣà kan náà. Òótọ́ni pé, àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́ ni àwọn Hausa apá àríwá, ní ìsọdá odò Ọya mọ̀ sí Yorùbá ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, kí orúkọ yìí tódi àjùmọ̀jẹ́ fún gbogbo ẹ̀yà.[20]

Èrò yìí fihàn pé, Yorùbá bí èdè tàbí bí ẹ̀yà ti wà tipẹ́; lòdì Òyìnbó aláwọ̀ funfun Bowdich pé ẹ̀yà Hausa ló sọ Yoruba l yìí.

Lọ́nà kejì, Fádípẹ̀ ní, pẹ̀lú ìmọ̀ràn látọ̀dọ̀ Sultan Bello tìlú Sokoto, Clapperton tó ṣàbẹ̀wò

sí ìhà ìbùgbé ẹ̀yà Yorùbá lọ́dún 1829, ẹ̀yí tó ṣàkàwé pé:

*the whole territory through which he passed on that journey as the country of the Yarriba and to the people themselves as Yarribans. This name he adopted from Hausa, who applied it, apparently, to the people grouped together as Yorùbá who were nearest to their territory, that is, the Yorùbá-Ọ̀yọ́ Kingdom. Clapperton obtained the information from the Sultan of Sokoto, on his first visit to Africa.*[21]

Ẹ̀yí túmọ̀ sí pé, Clapperton pe gbogbo ẹkùn tó gbà kọjá ní Yarriba, tó sì pe àwọn ènìyàn ibẹ̀ ní Yarriban. Orúkọ yìí ló mú látinú èdè tí Hausa fi peàwọn tó para pọ̀ ń jẹ́ Yorùbá, tí wọ́n ń gbé nítòsí wọn, èyí i nì ni ìjọba Yorùbá-Ọ̀yọ́. Clapperton gbọ́ ọ̀rọ̀ ìmọ̀ràn yìí látọdọ̀ Sultan tìlú Sokoto nígbà àbẹ̀wò rẹ̀ àkọ́kọ́ sílẹ̀ Áfíríkà.

Lọ́nà àkọ́kọ́, àwọn èrò òkè wọ̀nyí ṣàfihàn pé, àwọn àjèjì ló ń sọ ẹ̀yà àti èdè Yorùbá lórúkọ. Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, ọ̀dọ̀ olórí ẹ̀yà Hausá- Sultan tilẹ̀ Sokoto ni Òyìnbó aláwọ̀ funfun Clapperton ti gba ìmọ̀ràn orúkọ tí ìbá sọ Yorùbá. A lè sọ pé, abálájọ tí ìtàn àtọwọ́dọ́wọ́ ìṣaájú fi ṣègbè lẹ́yìn ẹ̀yà Hausá bí èyí tó bí Yorùbá, nítorí, kò sí ẹni tí ẹ̀ṣinsin yóò tún gbè, bí kò ṣe elégbò; ṣé bí a bá fún wèrè lọ́kọ́ ọ̀dọ̀ ara rẹ̀ ni yóò roko sí. Ìtàn àti ohun tó ṣègbè lẹ́yìn Sultan tilẹ̀ Sókótó ni yóò gbárùkù tì.

Ohun tó dájú ni pé, Ọ̀rúnmìlà ti wà ṣaájú ìgbàtàbí àkókò òwò ẹrú síṣe nítorí, ẹ̀rí wà pé ó kópa nínú òwò ẹrú. Ẹ̀rí látẹnu odù Ọ̀bàrà Méjì ẹsẹ karùnún sọ nípa Ọ̀rúnmìlà pé,





Baba l'ó ta Fúlàní ròdòdó.
Baba l'ó taáṣà l'ó ra Lárúbáawá.
Baba l'ó t'ẹrú n l'ó fi rọmọ.[22]

Ohùn ẹnu Ifá yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, Ọ̀rúnmìlà ra ẹ̀yà Fúlàní àti Lárúbáawa lẹ́rú láti ṣèrànpadà ẹ̀yà Yorùbá rí.

A ní láti ṣàkíyèsí pé, Ọ̀rúnmìlà tó jẹ́ òngbufọ̀ ohùn ẹnu Ifá jẹ́ Òrìṣà, bẹ́ẹ̀, ìtàn tó rọ̀ mọ́ ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn òrìṣà Yorùbá ni pé, rírọ̀ ni wọ́n rọ̀ láti ọ̀run. Òjíṣẹ́ Olódùmarè ni àwọn òrìṣà ní ìṣàlayé. Adéoyè ní, "Irinwó ni iyejú àwọn tí wọ́n rọ̀. Mẹ́rìndínlógún mẹ́rìndínlógún ni wọ́n ń rọ̀ mọ́ Ọ̀rúnmìlà ní rírọ̀ ẹ̀ẹ̀kan."[23] Èrò yìí fihàn pé, Ọ̀rúnmìlà bá ẹ̀yà àti èdè Yorùbá ní ayé (àwùjọ Yorùbá) ni. A kò rí ìtàn orírun rẹ̀ láti ìlú kan sí èkejì ṣaájú àárín ẹ̀yà àwọn Yorùbá. Ọ̀rúnmìlà jẹ́ agbẹnusọ fún àwọn ènìyàn, òkú-ọ̀run, àwọn òrìṣà àti ẹ̀mí-àìrí.[24] Èdè Yorùbá sì ni èdè ògbufọ̀ yìí. Bí a bá tẹ̀ lé ìtàn ìṣẹ̀nbáyé yìí, a lè fi gbogbo ẹnu sọ pé, àràbà ni bàbá, ẹni a bá lábà ni baba. Èdè Yorùbá ti wà tipẹ́, àti pé, Ọ̀rúnmìlà bá èdè Yorùbá nílé Ifẹ̀ ni, nígbà tí ó ti ìsánlú ọ̀run sọ̀kalẹ̀ sí ìsàlayé, nílé Ifẹ̀ Oòdáyé. Ifá/Ọ̀rúnmìlà ni a mọ̀ sí "Ọ̀npìtàn Ifẹ̀." Lójú Adéoyè,

> Yorùbá gbà pé nígbà tí Olódùmarè yóò dá 'ilé-ayé', Irúnmọlẹ̀ tí Ó fi iṣẹ́ yìí lé lọ́wọ́ ni Ọ̀rúnmìlà. Ìgbàgbọ́ wọn sì ni pé Ifẹ̀ Oòdáyé ni ibi tí wọ́n kọ́kọ́ dá àti pé ibẹ̀ ni Ọgbà Ìtẹ́rọ̀ tí í ṣe ibùgbé àkọ́kọ́ fún ọmọ ènìyàn wà. Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé Irúnmọlẹ̀ yìí ni ó mọ ìbẹ̀rẹ̀ tàbí ìpilẹ̀ṣẹ̀ ode-ayé, kò sí ìtàn Ifẹ̀ kankan tí ó sá pamọ́ fún un ni orúkọ inagijẹ yìí.[25]

Ẹ̀rí ìtàn mìíràn tó rọ̀ mọ́ èrò òkè yìí ni pé, àkọ́kọ́ kan náà ni a rí ìgbà ìwàláyé Odùduwà àti Ọ̀rúnmìlà. Lìjàdú ṣàfihàn rẹ̀ pé,

> *Ifá is a divination system created by the Yorùbá people of South Western Nigeria some 2000*

*years ago. In the course of succeeding centuries, The Ifá priests (Babalawo) have developed the original form bequeathed them by* ***ỌRUNMILA****, the reforming prophet of the* ***ODUDUWA ERA*** *of Yorùbá history (5000B.C. – 500A.D.) in many ways but have kept its canons essentially unchanged to this very day.*

Ifá dídá bẹ̀rẹ̀ látọdọ̀ ẹ̀yà Yorùbá apá Gúsù Ìwọ̀-oòrùn Nàìjíríà ní nǹkan bí ẹgbẹ̀rún méjì ọdún sẹ́yìn. Lẹ́yìn àwọn sẹ́ńtíùrì, ni àwọn àlùfáà awo Ifá ṣàwárí ojúlówó ìlànà ìdáfá tí **ỌRUNMILA** gbé kalẹ̀, ẹni tó jẹ́ wòlíì gbajúgbajà àkókò **ODUDUWA** nígbà ìtàn Yorùbá (5000B.C. – 500A.D.) lọ́pọ̀ ọ̀nà tó sì wà ní àìyí padà títí di òní.[26]

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìtàn ló wà nílẹ̀ nípa ibi tí Yorùbá ti ṣẹ̀ wá tàbí **tan** mọ̀. Àwọn onímọ̀ mìíràn bí I Johnson[27] àti Adéoyè[28] **gbà pé,** Yorùbá tan pẹ̀lú ilẹ̀ Égíbìítì. Ìdí sì nìyí tí wọ́n fi wòye pé, ọ̀rọ̀ **àyálò** ni ọ̀rọ̀ Ifá. Lójú Adéoyè,

> nínú èdè àwọn ẹ̀yà tí ó ń gbé Ilẹ̀ Égíbítì (Egypt) ni a ti yá ọ̀rọ̀ yìí lò. Èyí fìhàn gbangba pé, a ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú wọn rí. Nínú èdè àwọn tí a ti yá ọ̀rọ̀ yìí lò, 'ọgbọ́n' ni ìtumọ̀ Ifá. Dájúdájú nítorí Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ àti òye tí Irúnmọlẹ̀ yìí ní ni wọ́n fi sọ ọ́ ní Ifá. Ọ̀rọ̀ tí àwọn àgbà sì máa ń sọ pé 'Bí o gbọ́n, bí Ifá tí o mọ̀ràn bí ọ̀pẹ̀lẹ̀' kín àlàyé tí a ṣe lẹ́yìn.[29]

Bí a bá gbà pẹ̀lú àwọn onímọ̀ yìí, a jẹ́ pé, Ifá kò ní í ṣe pẹ̀lú **ìtumọ̀** rẹ̀, àti pé, ó ṣe é ṣe ká má ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ náà, kí a yá a lò. Jú gbogbo **rẹ̀** lọ, àríyànjiyàn yìí kò jẹ iṣẹ́ yìí lógún bí i èdè ìjẹyọ àti àmúlò èdè **ilẹ̀** mìíràn nínú odù Ifá. Ọdẹ́gbọlá ní "ní ilẹ̀ Lárúbáwá (Arabia),





*derb el rami* ni *Ifá*, wọ́n sì ńfi *Ọ̀rúnmìlà* pe Ṣẹ̀tìlù."[30]

Ìtàn mìíràn sọ pé Ṣẹ̀tílù ló pilẹ̀ Ifá dídá. Johnson ní,

> *another tradition says it was introduced into the Yorùbá country by one Sẹ̀tílù, native of the Nupe country...Sẹ̀tílù crossed the River Niger and went to Benin staying for a while at a place called Ọ̀wọ̀, thence to Ado. Subsequently he migrated to Ile-Ifẹ̀, and finding that place more suitable for practicing his art, he resolved to make it his permanent residence.*

> Ìtàn mìíràn ní ará Núpé kan tó ń jẹ́ Ṣẹ̀tílù ló bẹ̀rẹ̀ Ifá dídá nílẹ̀ Yorùbá… Ṣẹ̀tílù sọdá Odò Niger lọ sí Benin, ó dúró fúngbà díẹ̀ ní Ọ̀wọ̀, lọ sí Adó. Lẹ́yìn náà ló sí lọ sí Ilé-Ifẹ̀, nígbà tí ó rí i pé ibẹ̀ tu òun lára lati máa ṣiṣẹ́ Ifá dídá, ó yàn láti fibẹ̀ ṣe ojúkò ibùgbé rẹ̀.[31]

Ìdí tí a kò fi lè fi gbogbo ara daradé ìjóòótọ́ ìtàn pé Ṣẹ̀tílù ló pilẹ̀ Ifá dídá ni pé, èéṣe tó fi jẹ́ pé èdè ìdáfá rẹ̀ kò fi jẹ́ èdè Tápà, níwọ̀n ìgbà tó ti ń dáfá ṣaájú kó tó dé ibi tí a ń pè láàárín ẹ̀yà Yorùbá? Kò dájú pé, irúnmọlẹ̀ àjẹ̀jì lè sọ̀rọ̀ lédè tó yàtọ̀ tàbí ṣàjèjì sí èyí tó ṣẹ̀dá rẹ̀, níwọ̀n ìgbà tí ìmúṣẹ ìdáfá pé fún ìdàpọ̀ àwọn ẹmí àìrí. Bó bá tilẹ̀ jẹ́ pé, Ṣẹ̀tílù ló pilẹ̀ Ifá dídá, a jẹ́ pé, èdè Yorùbá ṣàgbà rẹ̀. Èdè yìí (Yorùbá) ló sì bí gbogbo odù àti ẹsẹ-Ifá. Ohun tó dájú tó àdá ni pé, èdè àti ẹ̀yà Yorùbá kò ṣe é yà nípa. Ìtàkùn tó so igbá ló so elégédé. Nílẹ̀ tó sì mọ̀ lónì ín, bí a ó bá ṣòwò Ògún, dandan ni kí a rajá. Babaláwo kò ní èdè mìíràn tayọ èdè Yorùbá láti ṣàṣeyọrí nínú ìdáfá. Bó bá sì ṣe àjọ̀jì ló fẹ́ kọ́ Ifá dídá, dandan ni kó jẹ́ nípasẹ̀ èdè Yorùbá.

**Àkójọ Èdè Fáyẹ̀wò àti Ìtúpalẹ̀**

Yaágbó-yaájù ni èdè Ifá. Ìdí nìyí tí Agboọlá fi ní "**nínú gbogbo** ọrílẹ̀-èdè àgbáyé èmi kò tíì rí ibi tí wọ́n ti ń lo èdè bíi ti **Ifá**."[32] Nípasẹ̀ irú èrò yìí, èdè àmúlò èdè àjèjì inú Ifá tọ̀nà ní **gbígbéyẹ̀wò** láti ṣàfikún ìmọ̀ wa nípa èdè àmúlò Ifá dídá.

Ẹ̀ka ohùn orin ẹnu Ifá, tí a mọ̀ sí ìyẹ̀rẹ̀ Ifá[33] ṣàfihàn **Ọ̀rúnmìlà** bí onímọ̀ tó gbédè, tó sì mèdè púpọ̀. Àtìlẹ́yìn èrò yìí ló **jẹyọ nínú** ìyẹ̀rẹ̀ Ifá pé:

Èlé: Ọ̀rúnmìlà súré ọọ m'édè,
wá kọ̀ mí
Ègbè: Súré kọ m'èdè wá kọ̀ gbogbo wa.
Ọ̀rúnmìlà súré ọọ m'èdè
wá kọ́ wa òò.[34]

**Ìyẹ̀rẹ̀** òkè yìí ṣàfihàn Ọ̀rúnmìlà bí olùkọ́ èdè púpọ̀, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ sì má **a ń tọ̀** lọ láti bomi ọgbọ́n èdè mu lọ́dọ̀ rẹ̀.

Àgbéyẹ̀wò àwọn odù àti ẹsẹ-Ifá kan fihàn pé, ìmọ̀ èdè, bọ́ **ṣe jẹyọ** nínú ìmẹ̀dèlò Ọ̀rúnmìlà ṣàpẹ̀júwe rẹ̀ bí onímọ̀-èdè tó **wàyàmì**, páàpáà, pẹ̀lú ìtọ́kasí èdè Tápà, Haúsá àti Lárúbáwá. **Abímbọ́lá** ní àmúlò ìmọ̀ èdè púpọ̀ wọ̀nyí ló ṣokùnfà orúkọ ìnagijẹ tí **Ọ̀rúnmìlà** ń jẹ́- "Ọ̀rúnmìlà Afèdèfẹ̀yọ̀."[35] Abímbọ̀lá ní èyí túmọ̀ sí **"Ẹni tí ó gbọ́ gbogbo èdè."**[36]

Ọ̀kan lára ìmẹ́dè àjèjì lò Ọ̀rúnmìlà nínú ohùn ẹnu-Ifá ló **jẹyọ** bí afọ̀ òwe Haúsá bó ṣe hàn nínú ọfọ̀ Ifá pé:

Ìpá-ǹlá-abùgbẹ-ṣ'ọ̀nà.
Ìpá-ǹlá-abùgbẹ-ṣ'ọ̀nà.
Ìpá-ǹlá-abùgbẹ-ṣ'ọ̀nà.
***Àngùlú-dè-kísò***
***Àngùlú-dè-kísò***
***Àngùlú-dè-kísò***[37]

Ọlábímtan sọnípa àwọn ìlà mẹ́ta tó gbẹ̀yìn ayọlò òkè yìí pé "àwọn





ọ̀rọ̀ tí mo fi àmì àkíyèsí sí nínú ayọlò òkè yìí fihàn pé, Èdè Hausa nìyí. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni 'Igún àti Onídìrí.' Nwọ́n ńfi pa òwe ni. Àpatán òwe náà ni 'Iná rú wá ná, àngùlú dè kísò – Kíni kan igún pẹ̀lú onídìrí'"[38]

Odù Ọ̀kànràn Ọ̀yẹ̀kú tún ṣàfihàn imédèlò èdè Haúsá pé:

***Rúwá ń yáá só, Rúwá ń yáá só***
***Rúwá ń sánmọ̀, Rúwá ń sánmọ̀***
Omi yáá rúbọ̀[39]

Sàlámì ní, "*Rúwan yan so ruwan sanmọ̀*. Both are Hausa words…It translates "Rain has come." The rain from the sky." Èyí túmọ̀ sí pé, àwọn ọ̀rọ̀ méjèèjì jẹ́ èdè Hausa tó túmọ̀ sí "òjò tí dé."[40]

Ọ̀rúnmìlà tún ṣàmúlò èdè Tápà nínú odù Ìrosùn Mẹ́jì ẹsẹ kẹjọ:

Bẹẹrẹ ló yẹ'lé
Àtẹ̀rígbà a yẹ ọ̀dẹ̀dẹ̀…
A díá fún Fátúsì
***LÉnpe***, n'lé àlété wỌya.
Afèdí ọkọ̀ tẹlẹ̀ fọ ***mọ̀gàmọ̀gà***.
Njẹ́ èdè àwọn lè yé ara àwọn báyìí?
Ni àwọn ara ***Ènpe*** dífá sí…
'Ọ̀pẹ̀ ń fọ Tápà,
Ẹ ò gbọ̀ ni
Ẹ̀dú mọ̀ mọ̀ ń fọ Tápà,
Ẹ ò gbọ̀ ni
Ọ̀pẹ̀ ń fọ Tápà,
Ẹ ò gbọ̀ ni.[41]

Nínú ayọlò òkè yìí, *LÉnpe* jẹ́ ìlú àwọn Tápà. Èyí tó fìdí àkíyèsí mi ìṣáájú hàn pé, àyẹ̀wò lọ́dọ̀ Ifá kò pin sọ́dọ̀ ẹ̀yà Yorùbá nìkan. *Mọ̀gàmọ̀gà* jẹ́ èdè Tápà. Orúkọ mìíràn tí Ọ̀rúnmìlà ń jẹ́ ni Ọ̀pẹ̀, tí oríkì orílẹ̀ rẹ̀ sì jẹ́ Ẹ̀dú.

Èdè Lárúbáwá náà jẹ́ èdè àmúlò inú ẹsẹ-Ifá. Bí àpẹẹrẹ, Odù

Ìká Méjì, ẹsẹ kẹta ni:

Ó ní atótó arére
Parákòyí, babaa *Mọ̀gánà*[42]

Abímbọ̀láni, *Mọ̀gánà* jẹ "àwọn tí ń fọ èdè Lárúbáwá."[43]
Ìjẹyọ èdè Lárúbáwá tún wáyé nínú Odù Òtúá Méjì pé:

***Wutùwutù yàákí;***
***Wutùwutù yambele.***[44]

Abímbọ̀lá ní, "Wutùwutù yàákí; wutùwutù yambele: a fi ń sín àwọn Ìmọ̀le jẹ́ nípa bí kéwúu wọn ti ń dún létí ẹni tí kò gbọ́ kéwú."[45]

Ibi ìjẹyọ àwọn èdè àjòjì wọ̀nyí níí ṣe pẹ̀lú ìṣewẹ̀kú àyè ìjẹyọ wọn nínú odù-Ifá tí wọ́n ti jẹ yọ. Bí àpẹẹrẹ, odù-Ifá Òtúá Méjì ló dá lórí bí àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà mẹ́ta- Gánmbí (àkọ́bí), Kìlàtù (èkejì) àti Dáúdù (ẹ̀kẹta) ṣe pilẹ̀ ẹ̀sìn Mùsùlùmí. Àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí:

Nígbà tó dọjọ́ kan,
Ni wọ́n bá ré agbádáa bàbá wọn,
Wọ́n ré gèlè Ìyáa wọn;
Wọ́n wọ agbádá náà,
Wọ́n sì wé gèlè náà sórí bàntùtù.
Wọ́n na igi mẹ́rin sílẹ̀ níbùúníbùú.
Wọ́n wáá kó sí àárín àwọn igi náà,
Wọ́n ńṣẹnu wújẹ́wújẹ́;
Wọ́n ńforí kanlẹ̀,
Wọ́n ńdìde,
Wọ́n ńkúnlẹ̀,
Wọ́n sì ńdìde
Wọ́n ńkúnlẹ̀,
Wọ́n ń naró.
Bàbáa wọn ṣá ńwò wọ́n ni.
Wọ́n ńṣe bẹ́ẹ̀ lẹ́ẹ̀maárùnúnmarùnún lójoojúmọ́...





Ìgbà tó yá,
Wọ́n wáá mú un bí iṣẹ́.
Ó di wí pé
Bí ẹnikan bá ńsọ ọmọ lórúkọ.
Àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ó lọ síbẹ̀.
Bí òkú kú fún ẹnikan,
Wọ́n á ránṣẹ́ pè wọ́n.
Bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ náàá ṣe
Tí wọ́n fi ńdàrà gbogbo.
Ìgbà tí wọn dàgbà tán,
Tí àwọn náàá bímọ.
Bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn ọmọ wọn náà ńṣe.[46]

Okùnfà ìṣàmúlò èdè Lárúbáwá kò ṣe lẹ́yìn àkóónú ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀sìn Mùsùlùmí pẹ̀lú àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta; bẹ́ẹ̀ ni orúkọ àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí sín wa ní gbẹ̀rẹ́ ìpakọ̀ pé orúkọ ajẹmẹ́sìn Mùsùlùmí tó tan mọ́ èdè Lárúbáwá ni àkóónú Odù Ifá yìí dá lé lórí. Ọ̀nà ìpàrokò tí a lè ṣàlàyé ìbátan rẹ̀ pẹ̀lú èdè àti ẹ̀sìn ni àwọn orúkọ wọ̀nyìí jẹ́. Ibi ìjẹyọ èdè- orúkọ nínú afọ̀, jẹ́ ọ̀nà ìtọpinpin ìbátan àṣà- nínú èyí tí èdè jẹ́ fọ́rán pàtàkì àti ẹ̀sìn.

Nírúfẹ́ ìṣàmúlò èdè àjèjì ní àyè ìjẹyọ báyìí, Mayle ní, a gbọ́dọ̀ mọ̀ pé,

> *much discourse is telegraphic. Verb phrase are not specifically mentioned, entire clauses are left out, ~~direct objects disappears,~~ pronouns abound. Yet, people still understand one another, and part of the reason is that rules of grammar and rules of discourse combine with contextual knowledge to fill in what is missing and make the discourse cohere. Much of the contextual knowledge is knowledge of who is*

> ***speaking**, who is listening, what objects are **being** discussed, and general fact about the **world** we live in – what we have been calling **situational context***
>
> pupọ̀ ìṣọ̀fọ̀ afọ̀ ló jẹ́ àfi-àmì gbé kalẹ̀. A kì í dárúkọ àpólà ìṣe ní tààrà, gbogbo awẹ́ gbólóhùn ni a máa ń gé kúrò, ohun tí a dojú afọ̀ kọ má a ń pòórá, arọ̀pò orúkọ má a ń wáyé. Síbẹ̀, awọn ènìyàn sì máa ń gbọ́ ara wọn ní àgbọ́yé, ọ̀kan lára okùnfà èyí sì ni pé òfin gírámà àti òfin afọ̀ máa ń papọ̀ mọ́ ìmọ̀ ọ̀gangan ipò láti dí àwọn àyè ohun tó ṣófo, tí ìṣewẹ́ẹ̀kú afọ̀ yóò sì wà. Púpọ̀ ìmọ̀ ọ̀gangan ipò jẹ́ ìmọ̀ aṣafọ̀, ẹni tí a darí afọ̀ sí, oun tí à ń ṣafọ̀ lé lórí àti bí ìgbé-ayé ṣe mú òòtọ́ dání sí – ohun tí à ń pè ní **àkóónú àyè.**[47]

Àgbéyẹ̀wò èdè Lárúbáwá tó jẹ́ ìfáàrà odù Òtúá Méjì òkè **yìí fìdí** èrò àyọlò òkè yìí múlẹ̀ pé, àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àpólà ọ̀rọ̀, pàápàá, **àpólà** ìṣe lè jẹ́ gbígbé fò ní àyè ìjẹyọ afọ̀ bẹ́ẹ̀ nínú odù-Ifá. Síbẹ̀ náà, **àgbọ́yé** máa ń wáyé, níwọ̀n ìgbà tí àkóónú àyè ìjẹyọ irú afọ̀ bẹ́ẹ̀ bá **ti ní** ìṣewẹ́kú, bó ṣe wáyé nínú àyọlò Odù Òtúá Méjì tíṣẹ́ yìí tọ́ka sí lókè. Àmọ́sá, ìjẹyọ èdè mìíràn nínú ẹsẹ tàbí odù-Ifá ṣàfihàn pé, Ọ̀rúnmìlà lóye àti ìmọ̀ àwọn èdè náà àti pé, ó ṣe é ṣe kí oníbèéré jẹ́ ẹ̀yà èdè ibi tí Ifá ti jẹ yọ. Bẹ́ẹ̀ sì ni, ìjẹyọ àwọn èdè àjèjì wọ̀nyí kì í ṣe èyí tí afọ̀ rẹ̀ jágùn ju gbólóhùn kan sí méjì lọ, nítorí, àmọ́, ní irú ìjẹyọ èdè bẹ́ẹ̀, kò wàrà ẹran rárá. Yíyọ àti kíkì odù, èdè awo Ifá-Yorùbá, ló gbọ́dọ̀ jẹ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ànfààní wà fún Ọ̀rúnmìlà láti ṣàlàyé fún oníbèérè lédè mìíràn tó yé tawo-tọ̀gbẹ̀rì, bí ó ti jẹyọ nínú odù Ifá tó ṣàfihàn pé, Ọ̀rúnmìlà gbọ́ èdè Tápà àti èdè Yorùbá bí iṣẹ́ ìwádìí yìí ti ṣàfihàn àmúlò àti ìjẹyọ irú ìmédèlò bẹ́ẹ̀ nínú odù-Ifá.





## Àgbálọgbábọ̀

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣàfihàn pé, àkóónú èdè Ifá gbòòrò, ó sì jìnlẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ tó ń ṣàfihàn Ọ̀rúnmìlà tàbí Ifá bí onímọ̀ elédè púpọ̀, bí iṣẹ́ ìwádìí yìí ti fìdí ẹ̀rí yìí múlẹ̀ pẹ̀lú ìjẹyọ èdè Haúsá, Tápà àti Lárúbáwá. Ó ṣe é ṣe kí okùnfà àmúlò àwọn èdè wọ̀nyí nínú odù àti ẹsẹ Ifá jẹ́ nípasẹ̀ ìbátan tàbí àjọṣepọ̀ ẹ̀yà Yorùbá pẹ̀lú àwọn ẹ̀yà èdè Haúsá, Tápà àti Lárúbáwá. Iṣẹ́ ìwádìí yìí tún ṣàtìlẹ́yìn èrò pé, Ifá ni eegun-ẹ̀yìn tó gbé àṣà Yorùbá, tó fi mọ́ èdè rò. Ìtàn Yorùbá tí a ò bá lè tọpinpin dénú Ifá àfàìmọ̀ kí irú ìtàn bẹ́ẹ̀ má jẹ́ òfegè ìtàn. Bẹ́ẹ̀ ni ìwádìí yìí ṣàfihàn Ifá bí "àdàbà kekelúwe" tí kò sí ọjà tí kò ná tán. Àmúlò Ifá, pàtàkì, ìjóòótọ̀ àti ìṣeédára-dé-fọ̀kàn-tẹ̀ rẹ̀ kì í ṣe láàárín Yorùbá nìkan, bí kò ṣe káàkiri àgbáyé.

## Ìtọ̀sẹ̀-ọ̀rọ̀

1. Wande Abímbọ́lá. *Ifá: An Exposition of Ifá literary Corpus.* (Ìbàdàn: Oxford University, 1976), 43.
2. T. Ládélé àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Àṣà Yorùbá.* (Ìbàdàn: Macmillan Nig. Limited, 1986), 62-3.
3. Wande Abímbọlá. *Ifá Divination Poetry.* (New York: Nok Publishers, 1977a), 31.
4. C. L. Adéoyè. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá.* (Ìbàdàn: Evans Brothers Nigeria Publishers, 1985), 173.
5. Ifalere Ọdẹ́gbọlá. *Ìwé miMmọ́ Ifá: Ẹ̀sìn Àkọ́dá Olódùmarè.* (Ìbàdàn: Ọdẹ́gbọlá traditional global services, 2014), 2
6. Akinṣọla. Akìwọwọ. "Understanding interpretative sociology in the light of the oriki Ọ̀rúnmìlà." *Journal of Culture and Ideas.* 1(1), (December, 1983): 48-9.
7. Wande Abímbọ́lá. *Ifá: An Exposition of Ifá Literary Corpus.* (Ìbàdàn: Oxford University, 1976), 3.
8. O. C. Orímóògùnjẹ́. "Ìfarasin ìbáku èrò àti ìgbàgbọ́ Yoruba nípa ìjìnjí Ifá." *Ọ̀PÁNBÀTÀ: Jọ̀na Ìmọ̀ Yorùba (LASU Journal of Yoruba studies).* 1 (November, 1993): 57.
9. O. C. Orímóògùnjẹ́. "Ìfarasin ìbáku èrò àti ìgbàgbọ́ Yoruba nípa ìjìnjí Ifá." *Ọ̀PÁNBÀTÀ: Jọ̀na Ìmọ̀ Yoruba (LASU Journal of Yoruba Studies).* 1 (November, 1993): 58.
10. J. Ọdẹ́yẹmí. Ifá and Òrìṣà Temple <oyekuofin.com/what-is-ifa/>2013.
11. B. A.Robinson, B. A. *Ifa*: the religion of the Yoruba people. March 3, 2012, http://www.religioustolerance.org/Ifa.htm,2008, 8





12. Wande Abímbọlá. *Ifá Divination Poetry.*(New York: Nok Publishers, 1977a), 31.
13. Ade Ọbáyẹmí. History, culture, Yorùbá and Northern factors. Nínú G. O. Olusanya(olóòtú.) *Studies in Yorùbá History and Culture,* ( Ibadan: University Press Limited, 1983), 7.
14. T. Ládélé àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀.*Àkójọpọ̀ Ìwádìí Àṣà Yorùbá.* (Ìbàdàn: Macmillan Nig. Limited, 1986), 62-3.
15. A. D.Areoye. "Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá: Ọ̀kan nínú ewì àbáláyé Yorùbá."1980, 7.
16. Awóníyì, T. A. *Yorùbá Language in Education.* (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1978).
17. Awóníyì, T. A. *Yorùbá Language in Education.* (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1978), 18
18. Awóníyì, T. A. *Yorùbá Language in Education.* (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1978), 18
19. Awóníyì, T. A. *Yorùbá Language in Education.* (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1978), 19.
20. E. M. Lijadu, as translated into English by Emanuel, Abọ̀sẹ̀de. (2010). *A Prophet Called Ọ̀rúnmìlà.* (Lagos: West African Book Publishers Limited,1908), xviii.
21. N. A. Fádípẹ̀. *The Sociology of the Yorùbá.* (Ìbàdàn: University Press, 1970), 30
22. Wande Abímbọlá. *Ifá Divination Poetry.*(New York: Nok Publishers, 1977a), 125.
23. C. L. Adéoyè, *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá.* (Ìbàdàn: Evans Brothers Nigeria Publishers, 1985), 29 Limited.
24. W. Abímbọ́lá. *Ifá: An Exposition of Ifá Literary Corpus.* (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1976).

25. C. L. Adéoyè. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá*. (Ìbàdàn: Evans Brothers Nigeria Publishers, 1985), 174.

26. E. M. Lijadu, as translated into English by Emanuel, Abọ̀ṣẹ̀de. (2010). *A Prophet Called Ọ̀rúnmìlà*. (Lagos: West African Book Publishers Limited, 1908), ix.

27. S. Johnson. *The History of the Yorùbás*. (Lagos: CSS Bookshops, 1921).

28. C. L. Adéoyè. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá*. (Ìbàdàn: Evans Brothers Nigeria Publishers, 1985).

29. C. L. Adéoyè. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá*. (Ìbàdàn: Evans Brothers Nigeria Publishers, 1985), 174

30. I. Ọdẹ́gbọlá. *Ìwé Mímọ́ Ifá: Ẹ̀sìn Àkọ́dá Olódùmarè*. (Ìbàdàn: Ọdẹ́gbọlá traditional global services, 2014), viii.

31. S. Johnson. *The History of the Yorùbás*. (Lagos: CSS Bookshops, 1921), 40

32. F. Agboọlá. *Ojúlówó Oríkì Ifá (Apá Kìíní)*. (Lagos: Project Publications Limited, 1989), v.

33. Oríṣìí ìtàn ló rọ̀ mọ́ ohun tí "ìyẹ̀rẹ̀ Ifá" jẹ́. Ọlatunji (bí Areoye 1980) ṣe ṣàfihàn rẹ̀, nígbà tó rí i bí ẹ̀yà ewì ohùn ẹnu Ifá tí àwọn Babaláwo máa ń sun; èyí tí Ọ̀rúnmìlà máa ń sun yàlà nígbà ìdunnú tàbí ìbànújẹ́. Areoye tún ṣàgbéyẹ̀wò èrò Abímbọ́lá (1976) nípa ìyẹ̀rẹ̀-Ifá pé, ohùn rẹ̀ máa ń yàtọ̀ gedegbe, èyí tó máa ń jẹ́ sísun lọ́jọ́ awo àti ọdún Imọlẹ̀. Ẹnìkan yóò máa lé e, tí ẹnìkan tàbí ọ̀pọ̀ èèyàn yóò sì máa gbè é.

Bí a bá wo ìṣẹ̀dá "ìyẹ̀rẹ̀" a le sọ pé "yẹ̀rẹ̀", èyí to túmọ̀ sí èkùkù lúbúlúbú láti ara igi gbígbẹ. Àwọn Babaláwo mìíràn máa ń fi tẹ̀fá. Àwọn babaláwo rí ìyẹ̀rẹ̀ bí ohun tí Ifá sọ.

Ìtàn mìíràn (ti ẹ̀rí rẹ̀ wà nínú Ifá) fihàn pé, ọmọ bíbí inú Ọ̀rúnmìlà ni "Ìyẹ̀rẹ̀." Ọ̀sán kan, òru kan ló fò sánlẹ̀ tó kú. Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá tí Areoye (1980) gbà sílẹ̀, ẹsẹ kọkàndínlógójì àti ogojì ní:

A dífá fún Ìyẹ̀rẹ̀
Tí s'ọmọ bíbí inú Àgbọnnìrègún
Àárọ̀ ẹkún ikú ọmọ Ọ̀rúnmìlà: Ìyẹ̀rẹ̀ mú kí àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù pàrọwà sí i pé kó mọ̀ sunkún mọ́, "ìyẹ̀rẹ̀ ni kí ó máa sun, nítorí kí irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ má lè wá mọ́"
Wọ́n ní ọ mọ̀ ṣunkún mọ́

ẹkún ìyẹ̀rẹ̀ ni ọ máa sun (Areoye 1980), 9. Èyí túmọ̀ sí pé, ohùn Ifá ni kó máa fi ṣẹ̀rántí/dárò ikú Ìyẹ̀rẹ̀. Èrò yìí ní àfijọ pẹ̀lú ẹ̀sìn Mùṣùlùmí tí wọ́n gbà pé dípò kí wọ́n máa sunkún Mùṣùlùmí tó kú, wákà ni kí wọ́n máa dá. Wákà dídá yìí yàtọ̀ sí kéwú kíké. Irú ìyàtọ̀ àti ìbátan láàárín Wákà àti kéwú ni a lè ṣàkàwé rẹ̀ bí èyí tó wà láàárín Ifá àti ìyẹ̀rẹ̀.

34. A. D. Areoye. "Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá: Ọ̀kan nínú ewì àbáláyé Yorùbá." 1980, 81.

35. W. Abímbọ́lá. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1968), 39.

36. W. Abímbọ́lá. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1968), 40.

37. A. Ọlábímtán. *Ewì Oríṣiríṣi*. (Ìbàdàn: Longman Nig. Limited, 1974), 35

38. A. Ọlábímtán. *Ewì Oríṣiríṣi*. (Ìbàdàn: Longman Nig. Limited, 1974), 35-6

39. A. Sàlámì. *Ifá: A Complete Divination*. (Lagos: NIDD Publishers, 2002), 406.

40. A. Sàlámì. *Ifá: A complete Divination*. (Lagos: NIDD Publishers, 2002), 448.

[41]. W. Abímbọ́lá. *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1977b), 30-1

[42]. W. Abímbọ́lá. *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1977b), 62

[43]. W. Abímbọ́lá. *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1977b), 66.

[44]. W. Abímbọ́lá. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1969), 96.

[45]. W. Abímbọ́lá. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1969), 99.

[46]. W. Abímbọ́lá. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. (Ìbàdàn: Oxford University Press, 1969), 96-8.

[47]. P. Mayle. More on situational context. Nínú V. Fromkin, R. Rodman àti N. Hyams (Àwọn Olóòtú) *An Introduction to Language*. (New York: Thomson Wadsworth, 2007), 204.